# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**Oṣù Kẹta, Ọdún 2024**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**AGBÁRA GBỌDỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́ OṢÙ KẸTA, ỌDÚN 2024**

**OJÚ TI GBOGBO ÀWỌN Ọ̀TÁ RẸ̀**

1. **Ha ẹgbẹ mi ẹ w'asia!**
Bo ti nfẹ lẹlẹ!
Ogun Jesu fẹrẹ de na,
A fẹrẹ ṣẹgun.

"D'odi mu, Emi fẹrẹ de"
Bẹni Jesu wi,
Ran 'dahun s'ọrun pe
"Awa o di mu".

2. Wo ọpọ ogun ti mbọ wa;
Eṣu nko wọn bọ;
Awọn alagbara nṣubu
A fẹ damu tan!

3. Wo asia Jesu ti nfẹ
Gbọ ohun ipe;
A o ṣẹgun gbogbo ọta
Ni orukọ Rẹ.

4. Ogun ngbona girigiri
Iranwọ wa mbọ;
Balogun wa mbọ wa tete,
Ẹgbẹ, tujuka!

1. **Ẹ̀nyin olùkórè nín'oko**
T'árẹ̀ fẹ́rẹ̀ mú tán
Ẹ rọ́jú dúró de Olúwa
Y'Ó s'agbára dọ̀tun

Àwọn tó dúró d’Olúwa
Y’ó s’agbára wọn d’ọ̀tun
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò
Nwọn ó fi ìyẹ́ fò bí ìdì
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n
Nwọn ó sáré, nwọn kì y’ó k’árẹ̀
Nwọn ó rìn, kì ó rẹ̀ wọ́n

2. Nígbà àrẹ́ àt’irẹ̀wẹ̀sí
À ngb’ọkàn wa sí Ọ
Lẹ́yìn t’agba Olùgbàlá gbọ́
Kí l’a ó tún bẹ̀rù?

3. Ẹ yọ̀! Ó mbá wa gbé lọ́jọjọ́
Àní títí d’ópin
Wòkè! ẹ sì ma tẹ̀sìwájú
Y’ó fùn nyín l’ágbára.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Àwọn agbára tó gbẹ́kẹ̀lé ìwà-ìkà lòdì sí mi, ejò ọ̀run látòkèwá yóò gbé yín mìn lónìí, ní orúkọ Jésù.
2. Àwọn agbára ìkà tó kórájọpọ lòdì sí mi, àrá Ọlọ́run yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n ti jẹ́ ẹ̀jẹ̀ búburú lòdì sí mi yóò kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ẹnikẹ́ni tó n kéde wí pé òun yóò kúkú kú dípò kí ó ri pé mo ṣerere, yóò gba itìjú lónìí, ní orúkọ Jésù.

5. Àwọn agbára tó nlọ sí ilé adáhunṣe láti dá ìràwọ̀ mi dúró, kí ó má lè dìde, ẹ gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, ìbínú Ọlọ́run yóò pa yín run lónìí, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn agbára àjèjì tó ní ìgboyà kíkún lòdì sí ọjọ́ iwájú mi yóò ṣubú lulẹ̀ kú lónìí, ní orúkọ Jésù.
7. Àwọn agbára tó n rìn jìnà láti ri pé mo sọkún, gba ọfà ikú, ní orúkọ Jésù.

## <u>ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ</u>

**ÌJẸ́WỌ́ - ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ẹnu òkùnkùn tó nfa ìgbé-ayé ètò-ìṣúná mi mu, gbiná, ní orúkọ Jésù.
4. Àwọn agbára tó nlo ìtàn mi láti gbóguntì mí, gba itìjú, ní orúkọ Jésù.
5. Àwọn agbára tó wí pé nkò ní gun àkàbà dé òkè, ya wèrè, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
6. Agbárakágbára tó n ṣàbẹ̀wò sí àwọn ìpàdé òkùnkùn pẹ̀lú orúkọ mi, wólulẹ̀, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ẹ̀dá ìkà, tó n dúró sárín èmi àti àwọn ibùkún mi, kú, ní orúkọ Jésù.

# <u>ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ</u>

**Ìsáíàh 40:29-31:** Ó nfi agbára fún alárẹ̀; Ó sì fi agbára kún àwọn tí kò ní ipá. Àní arẹ́ yóò mú àwọn ọ̀dọ́mọdé, yóò sì rẹ̀ wọ́n, àti àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin yóò tilẹ̀ ṣubú pátápátá. Ṣùgbọ́n àwọn tí ó bá dúró de Olúwa yóò tún agbára wọn ṣe; nwọn ó fi ìyẹ́ gun òkè bí idì; nwọn ó sáré, kì yóò sì rẹ̀ wọ́n; nwọn ó rìn, arẹ̀ kì yóò sì mú wọn.

**Ìsáíàh 57:18-19:** Mo ti rí ọ̀nà rẹ̀, èmi ó sì mú u lí ara dá: èmi ó sì tọ́ ọ pẹ̀lú, èmi ó sì mú ìtùnú padà fún u wá, àti fún àwọn aṣọfọ̀ rẹ̀. Èmi li ó dá èso ètè; Àláfíà, àláfíà fún ẹnití ó jìnà réré, àti fún ẹnití ó wà nítòsí, ní Olúwa wí; èmi ó sì mú u lí ara dá.

**Ìsáíàh 58:8:** Nígbàná ni ìmọ́lẹ̀ rẹ yóò bẹ́ jáde bí òwúrọ̀, ìlera rẹ yóò sọ jáde kánkán: òdodo rẹ yóò sì lọ ṣájú rẹ; ògo Olúwa yóò kó ọ jọ.

**Isàíàh 53:4-5:** Lótọ̀, Ó ti ru ìbìnújẹ́ wa, Ó sì gbé ìkánú wa lọ; ṣùgbọ́n àwa kà á sí bí ẹnití a nà, tí a lù láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, tí a sì pọn lójú. Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á lí ara nítorí aìṣedédé wa; inà alàfíà wá wà lára rẹ̀, àti nípa inà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.

**Isàíàh 41:13:** Nítorí èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́.

**Isàíàh 33:2:** Olúwa, ṣànú fún wa; àwa ti dúró dè Ọ́: Ìwọ ma ṣe apá wọn lí oròwúrọ̀, àní ìgbàlà wa nígbà ìpọ́njú.